# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

2022 ÌTÚSÍLẸ̀ ÀWỌN OBÌNRIN

Ilànà

- Lo ìṣẹ́jú díẹ̀ láti fi yin Olúwa
- Jẹ́wọ́ gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ tí o mọ̀ sí Olúwa
- Sọ fún Olúwa kí Ó múwá sí ìrántí rẹ gbogbo ẹ̀tọ́ tàbi àwọn ilẹ̀kùn àbáwọlé, tí àwọn ipá ìwà ìkà lè ma a lò láti fi rí àyè wọnú arà rẹ.
- Wọnú àkokò àdúrà tóní ipá lọ. Gba gbogbo àdúrà kọ̀ọ̀kan pẹ̀lú ìbínú mímọ́, ipá àti ikànran tóle.

Ìjẹ́wọ́: **Galátíà 3:13-14:** Krístì ti rà wá padà kúrò lọ́wọ́ ègún òfin, ẹnití a fi ṣe ègún fún wa: nítorítí a ti kọ ọ́ pé, ìfibú li olúkúlúkù ẹnití a fi kọ́ sórí igi: Kí ibùkún Abráhámù kí ó lè wá sórí àwọn kefèrí nípa Krístì Jésù; kí àwa kí ó lè gba ìlérí Ẹ̀mí nípa igbàgbọ́.

**Isàíàh 54:17:** Kò sí ohun-ijà tí a ṣe sí ọ tí yóò lè ṣe nkan; àti gbogbo ahọ́n tí ó dìde sí ọ ní ìdájọ́ ni ìwọ ó dà lí ẹ̀bi. Èyí ni ogun àwọn ìránṣẹ́ Olúwa, láti ọ̀dọ̀ mi ni òdodo wọn tí wá, lí Olúwa wá.

**Ìfihàn 12:11:** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Agùntàn na, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

1. Dúpẹ́ lọ́wọ́ Olúwa fún agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù tí kìí kùnà.
2. Olúwa, rìn padà sí ìpìlẹ̀ igi ìdílé mi, jẹ́ kí agbára ìwòsàn Rẹ farahàn.
3. Ní orúkọ Jésù, mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò nínú gbogbo ègún ìgbéyàwó àti ìrandíran.
4. Mo kọ̀, mo sì fọ́ gbogbo ègún àti ibọ̀dè tí wọ́n fi sórí ìgbé ayé ìgbéyàwó mi, ní orúkọ Jésù.
5. Mo gba àṣẹ lórí, mo sì de gbogbo ọkùnrin alágbára tí ó sopọ̀ mọ́ agbègbè ayé mi yòówù, ní orúkọ Jésù.
6. Ní orúkọ Jésù, mo fọ́ gbogbo ègún ìgbéyàwó tí àwọn ọ̀tá ìdílé fi sórí mi.
7. Ohunkóhun tówà nínú mi tí ó lòdì sí ìgbéyàwó, lọ báyìí, ní orúkọ Jésù.

8. Gbogbo ilànà ìgbéyàwó búburú ti ìdílé, fọ́, ní orúkọ Jésù.
9. Mo kọ gbogbo àsopọ̀ ọkàn búburú tó farasin, ní orúkọ Jésù.
10. Jẹ́ kí Ọmọ Aládé Alàfíà jọba nínú ìgbéyàwó mi láìní ìdíwọ́, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo agbára tó ndi rìkíṣí pẹ̀lú ẹnikẹ́ni láti pa ilé/ìgbéyàwó mi run, já ìdè rẹ, ní orúkọ Jésù.
12. Jẹ́ kí gbogbo agbára ibi tó n gbiyànjí láti tún atọ́ka ìgbéyàwó mi yà, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, sọ ìdílé mi di ohun tó n polongo agbára Rẹ, ní orúkọ Jésù.
14. Mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò nínú gbogbo adàlù àlá, ní orúkọ Jésù.
15. Jẹ́ kí gbogbo ohun tó lòdì tó n sákíri nínú ìṣàn ẹ̀jẹ̀ mi, maa jáde, ní orúkọ Jésù.
16. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, fọ ayé mi mọ́.
17. Àwọn fèrè yàfun àjẹ́ tó n dún láti inú ìpìlẹ̀ mi, láti lé àwọn olùrànlọ́wọ́ mi jìnà, kú, ní orúkọ Jésù.
18. Orí burúkú, àga ẹ̀yìn, ìgbé ayé líle tí wọ́n sọ sínú ayé mi, dópin, ní orúkọ Jésù.
19. Dá ọwọ́ kan lé orí rẹ, kí o sì dá èkejì sí inú tàbí ìdodo rẹ, kí o sì bẹ̀rẹ̀ siní gbàdúrà báyìí: Iná Ẹ̀mí Mímọ́, jó láti irun orí mi títí dé àtẹ́lẹsẹ̀ mi. Bẹ̀rẹ̀ siní dárúkọ gbogbo ẹ̀yà ara rẹ; kídìrí rẹ, ẹ̀dọ̀, ìfun, ẹ̀jẹ̀ àti bẹ́ bẹ̀ lọ́. O kò gbọdọ̀ kánjú ní àkokò yìí nítorí iná náà yóò dé, o sì lè bẹ̀rẹ̀ siní mọ ìmooru náà lára rẹ.
20. Dúpẹ́ lọ́wọ́ Olúwa fún ìdáhùn gbogbo àdúrà rẹ.